# EKO AKETE.

## IWE IROHIN OSOSE.

VOL. II. No. 55. SATURDAY, JULY 28, 1923. FOURPENCE.

**N. V. HANDLEMATTSCHAPPIJ V.H.**

J. F. SICK ati AWỌN ẸGBẸ.

No. 7, Ita Ibode Iailai, l'eti *Glover Memorial Hall*, (*Customs Street*,) EKO.





Awọn Oyinbo Onișowo yi nranșẹ MASINI-ARANSO ti a npe ni VESTA Nos. 1–4 t' ọlọwọ ati t' ẹlẹsẹ ni owo to rọju.

**A. KESSLER,**

GERMAN HAMBURG.

Mundlos on top Mundlos.

Iwọ le ranșẹ Ẹrọ-Iransọ "*Mundlos*," "*Adler*" ati Ẹrọ-riran bata ni 7, Labinjọ Lane.








A nranșẹ orisirisi ọja fun enia to tete nlọ nilẹ ni *Nigeria*.
A si nta Chun ẹrọ orin, Awo-Abọmafọ, Kẹkẹ-ologere, Waji.
E le ri ra lodọ J. S. Johnson, Alhaji Masu, ati H. Campos, ti Campbell Street.

Mundlos on top Mundlos.

## ỌGBẸNI J. C. VAUGHAN.

Ti Ile-Oja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Oja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni onirurú awọn ohun ẹlẹkọle fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O ti nsowo Irin Iṣẹ lorisirisi lati adọta ọdun sẹhin titi di oni.

ATAKI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ maa awọn onisowo Irin Iṣẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo po o.

---

## ỌGBẸNI DURO THOMAS

ONISOWO PATAKI.

Ti 55, ita Faji, l'Eko, ni orişirişi Ọja to de fun u lati Ilu Germany fun tita: awọn nkan Awo abọmafọ, Cement, Akara, ati ọpọlọpọ oja miran.

Ẹ lọ de ibẹ. Igbo-Akan 'mọpa ni ohun to ni.

Bi ẹ ba fẹ, ẹ kọwe si i, *Number* Apoti-Iwe rẹ ni Ile ipin iwe (*General Post Office*) ni 374. *Number* fifi-ẹrọ manamana ba a sọrọ (*Telephone*) ni 243.

---

## *Lagos Ekitiparapo Society.*

*Patron*: HIS HIGHNESS
THE OWA OF ILESHA.

The Council of the above Society respectfully request all Ekiti and Ijesha Children (Male and Female) who at present are not members of the above Society to register their names personally or by letter at the Office of the Society,

***Arapa Hall,***

[illegible]ms Street. The Secretary will be in attendance from 8 to 12 noon and 2 to 5 p.m. until 31st of August, 1923.

OGUNTOLA SAPARA,
*President.*

---

WHAT IS MORE REFRESHING than a sound sleep on a comfortable Bed? or time-saving than a thoroughly good sewing-machine?

A large consignment of Brass Iron-Beds, Bedsteads, (new arrivals from Germany.) is just to hand at Mr. Duro. Thomas's establishment 55, Massey St., Lagos.

An early call at this address for your selections will well reward your labour.

Prices attractive and alluring.

CALL TO-DAY NOT TOMORROW.

---

KILO NGBE MI LỌ YI O? ORUN!
AṢỌ NYIN FAYA, Ẹ LỌRAN.
AṢỌ NYIN FAYA, Ẹ LỌRAN.

IBUSUN-ILESANMI ati
MASINI-A-NJUWON

Ọgbẹni DURO THOMAS.

Onişowo-towolawi, ni awọn IBUSUN mèrémèré onidẹ to ṣẹṣẹ de fun u lati ilu Jamani wa fun tita ni Ile Ọja rẹ 55, Ita Mâse leti ita Faji, l'Eko.

Ifâ mbẹ fun awọn to ba tete lọ ra tiwon nibẹ: owo yẹpẹrẹ ni a nta wọn, bẹni awọn Ọja na si "ka 'yin" to.

E lọ ba Àwúre nyin pade nibẹ.

latı gbọ pe aida ara Lemọmu Braimah ko jẹ ko le lọ kirun fun awọn Jamma bi o ti nṣe l'ọdọdun ; a ro pe lati igbati a ti fi Alagba na jẹ Lemọmu Agba lẹhin iku Baba rẹ Lemọmu Gana ni iwọn lile ni ọgbọn ọdun ( 1890 ) eyi lo jẹ ẹkinni ti ko le lọ ki Ileya nitori aisan. A gbọ pe Naibi ti Ebuteawo l'o kirun fun awọn Jamma dipo rẹ. Ki Baba ṣe e ni fifuyẹ! Àgbò ọrun ni *Wednesday* ọsẹ yi ti o jẹ ọjọ ọdun ju ọkẹ aimoye lọ.

### ABỌ O. ỌMỌ-ONIFẸ.

. ki Ọgbẹni D. Ayọdele Bright ati obinrin rẹ pẹlu awọn ọmọde kabọ Ile-Ifẹ ti nwọn ti jẹ faji lọ, a gbọ pe Ọni Ọba Ifẹ gba Ọgbẹni na t'ọwọ t'ẹsẹ nigbati o de ibẹ ko si jẹ ko mọ ala ohunkohun titi o fi bọ wale: lọdọ Prince Adeyẹmi ọmọ Ọba Ifẹ ni Ọgbẹni yi wọ si o si rohin ohun pupọ ti o ri lọhun pẹlu pẹlu ni Kotu ọmọ Ibilẹ (*Native Court*) o sọ pe ẹjọ ti o wọpọ ni Kotu na ni ẹjọ awọn obinrin kọ-ọkọ-kọ-ọkọ pẹlu ọmọ jọjolo lọwọ!

O sọ ti iyẹsi ati ọyaya ti Ẹni-ọwọ P. V. Adebiyi ati Mrs. rẹ ṣe si wọn nigbati nwọn wọ si ọdọ wọn ni *Station* rẹ ti a npe ni Ẹdun-Abọn, o to ibusọ 8 si Ile-Ifẹ o si rohin bi Ẹni-ọwọ na ti mọ *Music* to, o ni nṣe lo nda ika (*fingers*) nọ lori duru tabi *Piano* nigbati o ba "*nplay*" o si ni Alufa na gba oye mimọ *Music* ti a npe ni F.I.G.C.M. ti *London*. Ọgbẹni Bright daro pe a ko fun irufẹ awọn Alufa Ijọ *Missionary* bayi laye lati jẹ ki wọn wa ma ṣiṣẹ l'arin wa l'Eko nibi, ati pe o dabi ẹnipe igbọ ni a nti irufẹ awọn Alufa to ni ẹbun [illegible] si, kiṣe ẹbun *Music* nikan, bikoṣe ẹbun Iwasu gbigbona pẹlu.

### ỌGBẸNI JACOBS, ỌRUN 'RE !!!

A ba awọn iyekan Ọgbẹni Joseph Jacobs ti 57, Patey Street, Ebute-Mẹta daro iku Ọgbẹni na to ṣẹlẹ ni ile rẹ ni *Wednesday* ọsẹ yi. Ọdun mẹsan gbako ni Ọgbẹni yi fi ṣiṣẹ ni *Bank* Nla ( B.B.W.A.) nibi, nipa biba awọn ti ko mọ 'we f' ọwọ si iwe-owo wọn ki wọn to le ri owo gba: Tani ko mo Jagun na pẹlu ẹwu iṣẹ rẹ—*Khaki* to fẹran ati ma wọ, ti yio si kẹ̀tẹ̀fẹ̀ sinu kẹ̀kẹ́ rẹ? Bẹ lo ri, Ọna ku, ohun ọwọ rẹ gbe 'lẹ.

Ki Baba f' ọrun kẹ ẹ.

### ALUFA OGUNKO, GBERE RẸ—!!!

A o fi Christ Church Ebute Mẹta ti Ijọ U.N.A. le Alufa John F. Ogunko lọwọ patapata ki o ma ṣe alufa rẹ ninu isin arọ ọla Feyiṣara, ọla a ro.

---

## ỌGBỌN AGBỌN JU OMUGỌ LO NDA SILẸ.

Ni alẹ Monday tio jẹ ijọ aisun ọdun awọn Imale mo ṣe eke ba wọn lọ wo *Cinema* ni Idunmagbo ti gbajumọ Saka Jojo fiwe si ode. Anu ṣe mi lati wipe nko gbadun ere na ati papa ẹrọ na ko gbamuṣe. Kini iba da eyi silẹ bikoṣe "mo gbọn tan."

Saka Jojo yi lo agba owo ni ẹnu ọna, on nikan na lo nṣere lọ yi ẹrọ. Enia to roju to fi owo tian tian ranṣẹ irufẹ ẹrọ nla yi tio si fi tagbaratagbara rẹ tun ile ẹrọ na ṣe. Kini de wayi ti ko le gba oniranwọ arara? Eyi jẹ abuku fun irufẹ olokiki enia bi Saka Jojo. Lotọ gbogbo wa lo mọ pe irun imu lowo ko ṣe fatu, ṣugbọn sibẹsibẹ Saka Jojo hu iwa alamọtan. Apakan san 2/- ẹlomi 1/- ẹlomi 6d ṣugbọn ẹnikẹni le joko sibi ti o bawun. Ni alẹ ijọ yi ọpọlopo awọn ara okere lo nwipe Ara Idunmagbo ki ṣe nkankan ko ya enia l'ori ri, iru ede yi nti mi loju pupọ. Nitorina a fẹ ki gbajumọ wa Saka Jojo lọ ro ọrọ na wọ daradara, nitoripe "enia kan ki jẹ ki ilẹ fẹ." A ki Saka ku inawo ẹrọ na ki Ọlọrun jẹ ki o ri ẹmi lo "Abọ ọrọ la so f' ọmọ lu wa bi"

OMỌ EKO.

---

## THANKS FOR SYMPATHY.

Mrs. D. J. Williams and family beg to return sincere thanks to all those who by personal calls, letters and telegrams have sympathised with them in their recent bereavement by the death of Mr. D J. Williams at Ilesha.

## "WOSIKA."

*Lati ọwọ Ẹni-Ọwọ I. O. Oyekunle.*

II.

Nigbati awọn enia wọnyi ri wipe a gba wọn ni anfani ati ma ṣe iṣẹ okunkun yi, bi Bibeli ti wi pe "Awọn enia fẹran iṣẹ okunkun, nitori ti iṣẹ wọn buru." Ni ọdun diẹ sẹhin a si tun gbọ wipe awọn enia wọnyi si tun wariko wipe awọn yio ma ṣe Egungun dipo Oro, eyi ti a ti gbọ wipe o jẹ ewọ ilu na. Ni ẹnu lọlọ yi a ri irohin gbọ wipe wọn ṣe Egungun kan nibẹ, ati wipe awọn Egungun meji kan jade eyiti wọn npe ni "Alajoyi" ati "Elebute" a gbọ wipe owo ti nwọn na lati fi ra ohun ọṣọ si ara Egungun mejeji yi le ni pọnwun mẹrindinlọgọta (*over* £56,) kaka ki a na owo iyebiye yi sinu Ile Ọlọrun tabi ki a fi ṣe ohun rere kan fun ilu wa, a na gbogbo owo banta-banta yi sori ohun lasan, kini Bibeli ti wi, "Ẹ maṣe ko iṣura jọ fun ara nyin ni aiye ni bi ti kokoro ati ipara ibajẹ" "kaka ko san lara ajẹ, o nfi ọmọ rẹ b'obinrin ẹiyẹ nyin ẹiyẹ" ka ka ki awọn enia wọnyi ma jowu ọrọ Ọlọrun nṣe ni nwọn njowu iborisa. Ogo ha da ninu eyi? Ki si iṣe eyi nikan, a si tun gbọ wipe awọn to jẹ onigbagbọ pẹlu si tun nba wọn ko aṣọ Egungun bori lati ma ke bọ ọ kakiri ita "Ephraim ti dapọ mọ oriṣa" eyi ko ha jẹ ohun itiju. kini iwasu ti awọn wọnyi yio wa lọla fun awọn aboriṣa A! iwọ Onigbagbọ oju ko ha ti ọ? Kini ohun to tun fi ju awọn aboriṣa lo nisinsinyi. Iru iwa bayi ni Jeremiah ri ti o fi sọkun kikoro lori Jerusalem. A! iwọ Onigbagbọ ti o di onigbagbe lọ ka Iwe *Matt. 23. 13.* ko si fi we ipo rẹ nisinsinyi. Ni ipari, mo ke si ẹnyin Onigbagbọ, ati ara ilu, ẹ ma jẹ ki ibinu Ọlọrun wa sori a bi ti *Sodom* ati *Gomara*. Gbọ bi iwe iwasu ori kejila ẹsẹ kini ti wi: "Ranti lẹda rẹ nisinsinyi li ọjọ ewe rẹ, nigbati ọ ibi ko ti de, ati ti ọdun ko ti sunmọ tile, nigbati iwọ o wipe Emi ko ni inu didun ninu wọn." O d'ọwọ nyin o! Bo a baje ẹnyin ni o.

Mo dupẹ lọwọ rẹ, Editor "Eko Akete" fun aye diẹ ti o gba mi.

## IBERE NI IDAHUN.

Bère-bère ki iṣi bère. Oyeneyẹ l'o bère ọrọ; ẹniti o ba bère ọrọ l'asi da lohun.

Ninu "EKO AKETE" ti June 30, Page 7, Oyeneyẹ bère ṣoki pe, "Tani le ka orin yi" (ti o wa nisalẹ) "si ọkan ninu ohun orin ilẹ wa, orilẹ-ede wo lo ni irufẹ orin to lọ bayi, wi ki ngbọ"?

*m* : *m* :— | *s* : *s* : | *d*, : *m* : | – – – – – – ‖
*d'* : *d'* :— | *l* : *l* : | *s* : | – – – – – – – – ‖
*m* : *m* :— | *s* : *s* : | *r* : *m* : *d*, : | – – – ‖
*m* : *m* :— | *r* : *r* : | *d*, : | – – – – – – – – ‖

**MO WI KI O GBỌ,** emi ka orin **yi** si ohun orin ilẹ wa; ọrọ rẹ si lọ bayi:—

Iwoyi Amọdun,
A o t'n Ọba jẹ;
Asa jẹ ni t'ọsanyin,
Ewe jẹ l'oko.

Orin Ijẹbu ni: awọn Onibukù ni isi ma kọ orin na l'akoko ọdun bukù wọn; laisi ani-ani, mo ro pe Oyeneyẹ yio ni itẹlọrun si *Pẹrọ* ti mo ja yi.

A. ỌLA. AJIB.

## O KARE, ỌMỌ AFINJU ỌLỌJA T'O S' ỌYỌ RO. !!!

O nsunmọ ọdun mẹjọ nisisiyi ti Ọgbẹni T. I. KESTER ti nṣiṣẹ ni ibi iṣẹ awọn Olotu ilu; (*Police Department*), lati igbati o ti nṣe iṣẹ rẹ na ni Kotu Ọga awọn Ọlọpa (*Criminal Prosecutor, Police Magistrate's Court*) titi fi di oni, ni a ngbọ lẹnu awọn ọgọrọ enia ati awọn Akọwe Kotu ati awọn *Lawyer* pe Ọgbẹni ti a nwi yi ja fafa ninu iwe ati pe o si mọ iṣẹ rẹ de gongo, eyi mu ori wa ṣi lọpọ-lọpọ; irufẹ iyin yi lo mu wa kọ iwe ayọ nipa Ọgbẹni na sinu iwe irohin ọsọsẹ *The Lagos Standard* ti oṣu *September 1915*, kete ti a gbọ pe o bọ si ibi iṣẹ pataki na. Ẹnikẹni to ba sunmọ Ọgbẹni na yio mọ pe gẹgẹ bi o ti ja fafa bayi ti o si nipo ninu iṣẹ rẹ, ko jẹ fi oju pa ẹnikẹni rẹ, ibaṣe olowo tabi talaka.

LALẸYẸ.

A ko fẹ ki Ọgbẹni yi sọ, bi o ba ri iwe irohin yi ka, pe, a npon on ni, bẹkọ rara, o jẹ iṣẹ wa lati sọ gbolohun ọrọ meji tabi mẹta yi fun iṣiri awọn ẹlomiran ninu awọn ọmọ Yoruba larin wa nibi tabi nibomiran.

Njẹ ajinde ara a ma jẹ ọ, Ọgbẹni, ọkanṣoṣo Araba t' ẹgba Ọṣuuṣun !!!

---

**EKO AKETE.**

EKO, SATURDAY, JULY 28, 1923.

---

ARA, Ẹ MA JẸ O RẸ NYIN.

Kẹlẹkẹlẹ ọjọ yiyan enia sinu Ajọ Igbimọ nku fẹfẹ; a si dupẹ pe awọn Ẹgbẹ Ilu *Nigeria* (*Nigerian National Democratic Party*) ko sun rara nidi ọrọ na; ẹnikẹni t'o ba wa si Ipade wọn l'ọsẹ t'o kọja, gẹgẹ bi a ti rohin rẹ sinu Iwe-Irohin ọsẹ yi, yio ri pe awọn Olori ati gbogbo awọn ọmọ-ẹgbẹ na ko jafara iṣẹ ribiribi yi, bi-ere-bi-ọwa oṣu *August* nwọ ile, a si gbọ pe ọpọlọpọ ipade opopo ode ni awọn Ẹgbẹ yi npete ati ṣe pẹlu awọn enia lati tubọ sọ ohun ti nbọ nipa enia-yiyan yi fun gbogbo ilu ko si ye wọn yekeyeke. Ẹ o si ri pe awa enia dudu nikan kọ ni ọran yi dun mọ ninu; ẹniti o ba ka "Wosika" gbayawu ti a fọ si Adele Gomina Sir Donald Cameron Ọlọla nla, ni ede Gẹsi ti a si tẹ si apakan iwe yi, yio ri ọrọ ti Adele na sọ gẹgẹ bi Anfani ti a yọda fun Ilu Eko ati Calabar, lati yan enia si Igbimọ Aṣofin Ijọba na ti dun mọ on to. Ẹnyin ara, ẹ ko wa ri wayi pe, ẹniti o ba dakẹ ti ara rẹ a ba dakẹ? Njẹ ki o jẹ pe a dakẹ ni nkọ, pe ko kan wa ko kan wa, njẹ ẹgọ kan ha le yẹ wa bẹ?

Nitorina afara ko si ni ọrọ na: ki ọkunrin tun ṣokoto rẹ san giri, ki obinrin si tun ọja rẹ fun.

A si dupẹ lọwọ Ọgbẹni Herbert Macaulay C.E. Arọ-ma-da-hun ọkọnrin ati Ọgbẹni J. Egerton Shyngle fun aisun-aiwo wọn lati igbati ọrọ yi ti de lẹ.

Ara àgbà ki ṣe ere ẹlẹ o, ẹ jẹ ka ṣe e ko yẹ wa.

Yiyẹ ni iyẹ ẹiyẹle !!
K'o ṣẹ k'o ṣẹ ni ti Ilakọṣe !!!

A-a-a-ṣọ.

---

ILU EKO.

Si Oniwe-irohin, "EKO AKETE."

Jọwọ, ma ṣai fun mi l'aye diẹ ninu iwe-irohin ẹ lati fi esi si ọrọ ti Ọgbẹni Ṣodẹyinde sọ rni alẹ ijẹfa ni Mọṣalaṣi wọn, nibiti nwọn nṣe aisun-ọdun ti nwọn ṣe nijarun.

A sọ fun mi pe Ṣodeyinde nsọ fun awọn Jamma (*Congregation*) rẹ pe, a pe wọn si ibi Isin kan ni lọlọ yi; awọn to pe wọn nbọ olori wọn gẹgẹ bi awọn ara igbani ti sọ Ṣango, Ọya ati iru nkan ba wonni di oriṣa. Bi eyi ba ri bẹ, o jẹ iyalẹnu fun mi lọpọlọpọ pe iru Ọgbẹni Ṣodẹyinde ti a nri orukọ rẹ l'ọsọsẹ ninu iwe-irohin yi fun aṣiwaju ninu isin wọn owurọ, nsọ boto.

Ṣodẹyinde ko ṣai mọ pe awa ki nṣe Ijọ to nbọ Kristi Jesu, Ọga ninu awọn Messiah.

Kini a npe ni Messiah? Messiah ni ẹniti o kọ enia lọna isin otitọ, tabi to fi otitọ inu isin Ọlọrun han.

Ṣodẹyinde, Tani Ahmad nṣe?

Tabi Ṣodẹyinde le sọ pe ẹniti a npe ni Messiah yi ko kọ enia lọna isin otitọ Ọlọrun ju awọn isin iyoku lọ ni Naijiria loni?

Mo ṣebi Ṣodẹyinde gba a pe Ọlọrun ma ngbe enia dide lakoko kọkan lati ko ni, tabi ko gba a? Njẹ bi o ba gba a, tani iwọ fi . . . . . . . npe?

Mo tun bi ọ lere, Gbogbo Ajẹlẹ to ti nwa si Naijiria, ewo ninu wọn lo gba oye to Sir Frederick Lugard? Tabi awọn to ku ki nṣe Ajẹlẹ bi?

"Imọran mi fun Ṣodẹyinde ni pe, ki o maṣe tun ṣẹ 'gi era mọ; bi a ba ni mọ, ẹmọran a mọ."

Mo dupẹ lọwọ rẹ, Oniwe-irohin EKO AKETE.

ATAKOLO.

---

O-KU, MỌDE IRAYE.

Irohin kan ni wipe Ọgbẹni Francis Elias Silva (baba Yetunde) ọmọ O. le kinun ni Ita Ọbadina, fi iṣẹ silẹ ni oṣu yi, ni ile iṣẹ rẹ S. Thomas & Co., fi isimi, lẹhin ọdun mẹtadilogun.

## Open Letters.

TO CELEBRITIES, NOTORITIES, ETC., IN DIFFERENT WALKS OF LIFE.

No. 27.

To HIS EXCELLENCY

SIR DONALD CAMERON, K.B.E., C.M.G.;

*Acting Governor.*

Government House,

Nigeria.

YOUR EXCELLENCY,

Your peroration in windingup the business of the last Legislative Council under the old *regime* as contained in the proceedings of that august body which came under my notice recently is noteworthy; particularly when in a very fitting manner, you congratulated honourable members on its demise in these characteristic lines.

"Honourable Members of the Legislative Council of the Colony of Nigeria:

You are all aware that the new Letters Patent and Orders in Council referred to in the Ordinance passed to-day come into effect on the 1st June, 1923, by virtue of a Proclamation recently issued in the *Gazette:* in consequence this Honourable Council will cease to exist on May 31st next and, as there is no more business to be transacted as far as can be seen, this will probably be the last time Honourable Members will be summoned to this Council. The Legislative Council of the Colony of Nigeria will thus cease to exist after a life of over nine years.

It is not my intention to deliver a funeral oration on the present occasion. To be frank—and there is no reason to dissemble my views—I experience a sensation of joy rather than of regret at its decease; at the decease of a Council which for the past nine years has had no financial control and only very fragmentary powers of legislation. It will cease to exist and will be succeeded by a Council endowed with a generous measure of financial control and with legislative powers of a much wider description. These increased powers will prove, I hope, a potent power in shaping and directing the energies and the destinies of this great Dependency. This Council will die, but from its ashes (shall I say ?) will arise another and stronger body in which, for the first time in the history of British West Africa, representatives of the people directly elected by themselves will be able to give expression to the views and aspirations of the inhabitants not only of the Colony but also of the Town of Calabar. I wish you, Honourable Members, an unmournful farewell and declare that this Council do stand adjourned without date."

It goes without saying that your Excellency welcomes the Dawn of the New Era wholeheartedly, as evidenced from your speech which can safely vie with the oratorical power of a Burke or a Sheridan in the republic of letters: Nigeria, I make bold to say, is greatly indebted to you, Sir, for this frank pronouncement on a subject which the bulk of the inhabitants of this growing Dependency hold dear; and it is to me a matter of no small satisfaction that those of our own colour—the old contemptibles, shall I say?—who, during the last few years, have shouted themselves hoarse in more ways than one, against the introduction of this small, but all-important measure of Representative Government, will be thoroughly ashamed of themselves on reading your speech, as to ejaculate *Peccavi!!!*

Your Excellency is by nature, a man of *few* words with a large amount of administrative tact and experience, and your view such as the above, will undoubtedly be treasured up by many an African, as coming as it does, from one whose sole aim is always to dispense even-handed Justice to all without fear or favour, affection or ill-will.

Countrymen, Hats off to Sir Donald Cameron!!!

EKO AKETE.

---

Editor Eko Akete.

Jọwọ maṣai fun mi ni aye kekere ninu iwe rẹ lati dahun si ọrọ Oyenẹyẹ bayi pe :—

Ronu ni ẹrinmeji ki o to sọrọ lẹkan.

Ninu iwe irohin Eko Akete to jade ni ọjọ kẹtalelogun oṣu *June* (23/6/23) ni ewe karun iwe na (*Page* 5) Ẹnikan ti o pe ara rẹ ni Oyenẹyẹ so bayi pe.

"Iwa aitọ ti o wa fun awa enia dudu nipe ohun ti olukuluku ba dawọle ni ṣiṣe nikan ni o nkun u loju, a ki si fẹ gbe iṣẹ ọm'ẹnikeji wa ga."

Lẹhin ti o sọ bẹ tan o wa tọka si ohun orin ilẹ wa meji ti awọn apapọ ijọ enia dudu fi ṣe isin isọji ni eṣin (1922) o sọ pe: "Ọdọmọkunrin kan ṣe orin kan eyiti ila kini ninu ẹsẹ kini lọ bayi :—

"Baba to ni wa awa de."

Oni oṣu mẹfa lẹhin ti ọrọ orin na jade, ẹnikan dide lati wa (*Compose*) ọrọ fun ohun orin kan na, ila kini ninu ẹsẹ kini orin na lọ bayi :—

"Baba aiyeraiye awa de."

Ohun kini ti mo kiyesi ninu ọrọ Oyenẹyẹ nipe o dabi ẹnipe o ngbeja ọrẹ rẹ nitori o fi han gbangba pe ẹni mimọ on ni ẹni ti o kọkọ ro orin na, o ni "ọdọmọkunrin kan" lotọ o yẹ ka gbeja ọrẹ ẹni ṣugbọn ko tọ ka gbeja ẹnikẹni lori ẹbi; njẹ nitori jija ti Oyenẹyẹ jalu ọrẹ na logedengbe bayi ni ngo ṣe fun ni oriki yi :—Oyenẹye di a gbe fun ẹlẹbi timọ a gbe ejọ elejọ wọmi.

Ni ọna keji nko mọ bi onigbagbọ tabi imale tabi keferi ni Oyenẹyẹ, ṣugbọn eyikeyi ti owu ko jẹ o tọ ki o mọ pe oniruru ni ibanujẹ ati ẹdun olukuluku enia, nitorina adura ati ọrọ orin ni lati yatọ sirawọn ni orişirişi, bẹ na si ni igba idupẹ igba ikanu ati igba miran, bẹ gẹgẹ li a si ni lati ro oniruru ọrọ orin to le ba awọn oniruru asiko wọnyi mu ni (*tune*) ohun orin kanṣo.

Bi o ba wo iwe orin ti ijọ *C.M S.* tabi *Wesleyan* tabi orin ilu tabi orin oriṣa ao ba bẹ. Ẹniti o ro orin yi ni iṣiwaju fẹ orin na fun isọji, ṣugbọn ẹniti o ro tirẹ lẹhin oṣu mẹfa ro tirẹ lati ba idipalẹ ile Ọlọrun mu, fun lọ joko ki o ka ọrọ orin na delẹ daradara wa ri pe ko si aitọ nibẹ iwọ ni o ko ronu lerin meji ki o to sọrọ lẹkan, mo dupẹ pupọ lọwọ rẹ Mr Editor fun aiye ti o fun mi.

Emi ni tirẹ nitotọ

ỌLABOYẸ LALẸYẸ.

IGBẸ L' OWO WÀ.

LAGOS—EKURO.

Bi awọn oyinbo ile-òwò wọnyi ti gba Ọja (*Produce*) l' ọsẹ yi ni eyi.

Ẹgbẹ Odo-Ọya (Niger Co.)
G. B. Ollivant.
Oyinbo Agbẹra (Lagos Stores)
MacIver, African Association, John Holt, Miller Bros. Cooperative Wholesale Society Ltd., Jurgens Colonial Product.

£12 10—£13 fun *ton* kan.

EPO

£23—£24 ni gbogbo awọn Ẹgbẹ oyinbo ti a darukọ wọnyi gba *ton* kan.

COCOA.

£25—£26 fun *ton* kan bakanna.

KANO—COMPETITIVE PRICES

Ground Nut—

Skins 1/11½ per lb, Hides 4½ per lb

**POSI T'O JIRE.**

Ẹnikẹni le ri awọn Posi alarabara ti a ti ṣe lọṣọ lati Ilu Ọba wa ra ni ile ọja Kọlade ni 40A Joseph Street, Okepopo, ati ni No. 1, Moloney Bridge St., Anikantamọ. Ọtọtọ ni iye owo wọn, lati £6. 6. titti de 25 guineas. Aṣọ oku (*Shroud*) Yọmini to funfun bi lekeleke si wa nibẹ fun tita pẹlu.

Ẹ lọ ri tabi ki ẹ kọ'we si:—

Ọgbẹni HUDSON COLE,
P.O. Box 477,
Eko.

**MR. A. KESSLER,**

7, LABINJỌ LANE, WILLIAMS STREET, LAGOS.

**Pilsener Beer! Pilsener Beer!!**

*One's thirst is quenched on taking a glassful*

"LION BREWERY BRAND"

**Reduced to 32/- per case.**

*A TRIAL, FRIEND.*

Ọgbẹni na ni Ọti *Beer* tò yo-lù-wá ni tita ṣile mejilelọgbọn pere ni fun Apoti kọkan· Igbadun mbẹ nibẹ ẹ jare. Ẹ rẹ tọ wò.

*Telegraphic Address* :—**BANK ANTHONY**

TOKUNBO, LAGOS.

Telephone No. L230, G.P.O. Box No. 300.

*Residence and Office 137 Tokunbo Street Lagos.*

Ọgbẹni A. BANK ANTHONY AND SONS jẹ Onisowo to nranṣẹ ọja fun tita lati ilu ọba ( *England* ) wa. O si ma nfi ọja ṣọwọ sibẹ na pẹlu.

Diẹ ninu ọja tı o ma nra ni ilẹ yi ti o si ma nranṣẹ ni wọnyi :—

Gẹdı. Rubber, Cocoa, Ekurọ, Epo. Ọbi, Igi Osun, Agbado, Iwo Malu, Awọ orişirişi.

Diẹ ninu awọn ọja ti o ma nranṣẹ fun lati Ilu Ọba ( *England* ) wa fun tita ni ilu wa ni wọnyi. Aşọ orişirişi, Akara Ôyinbo, Ẹran oniyọ ati ọpọlọpọ nkan miran bi iru eyi ti o ta ni ilu wa ati Posi isinku iru eyi ti awọn oşişẹ wa ko le şe ni ilẹ wa.

Wo aworan ọkan yi, wa si ri daju pe awọn oşişẹ ilẹ wa ko le şe iru rẹ.



Irohin ko to afojuba lọ si ile rẹ. No. 137 Tokunbọ Street wa si ri daju pe ki işe ti asọdọn o ni ti talaka o si ni ti Olowo eyiti a fi igi şe tabi eyiti o jẹ onidẹ ( Brass )

Ẹ kọwe tabi ki ẹ ja waya si i a o si fi Posi ranşẹ si nyin nibikibi ninu *Motor Transport.*

## Preachers for To-morrow.

AWỌN ONIWASU ỌLA.

ROMAN CATHOLIC (HOLY CROSS)

Masses will be sung by Priests appointed.

Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo akoko wonyi.

(MORNING)

Masses Isin Arọ.

6.30 7.30 8.30 9.30
7.30 8.30 9.30 10.30.

(EVENING.)

Masses (Benediction) Isin Ibukun.

4.45—5.30 6.45—7.30.

ST. MICHAEL'S (Lafiaji.)

MORNING. 7 a.m.—8 a.m. 8.30 a.m.—9.30 a.m.
EVENNING. 5.45—6.30 p.m.

ANGLICAN

| Time. | | Preacher. |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Christ Church | The Vicar |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m.— | St. Paul's (Breadfruit) | Ven. Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi |
| 6.30 p.m. | | do. |
| 9 a.m. | St. John's (Aroloya) | Rev. H. V. E. Johnson |
| 6.30 p.m. | do | do |
| 9 a.m. 6.30 p.m. | St. Peter's (Alapako) | Rev. J. A. Cole |
| 9 a.m. & 6.30 p.m. | Holy Trinity (Ebute Ero.) | Rev. S. J. Gansallo |
| 9 a.m. | St. David's (Jordan) | Rev J. A. Leigh |
| 6.30 p.m. | | do. |

WESLEYAN

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | Tinubu | Rev. A. N. Cole |
| 7 p.m. | do. | Rev. S. A. Pearse |
| 10.30 a.m. | Ereko | Rev. E. K. Ajai-Ajagbe |
| 7 p.m. | do. | do. |
| 10.30 a.m. | Olowogbowo | Rev. E. E. Williams |
| 7 p.m. | | Rev. A. N. Cole |
| 10.30 a.m. | Obun Eko | Rev. S. A. Pearse |
| 7 p.m. | | Bro. N. A. Thompson |

AFRICAN (COMMUNION)

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Jehovah Shalom | Rev. M. B. Newton |
| 7 p.m. | do. | ,, J. F. Ogunko |
| 9 a.m. | Erelu | Bro. Ignatius Williams |
| 7 p.m. | do. | Bro. J. H. Lawson |
| 9 a.m. | Bethel | Rev. N. J. D. Somuji |
| 6.30 p.m. | | Bro. J. H. G. Willoughby |
| 9 a.m. | Zion | ,, A. O. Thomas |
| 6.30 p.m. | do. | Rev. J. A. Wright |
| 10.30 a.m. | African Methodist | Bro. J. A. Oshodi |
| 4.30 p.m. | | ,, Samuel Johnson |

FIRST BAPTIST CHURCH

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | | Bro. A. T. Openiyi |
| 4.30 p.m. | | Rev. J. R. Williams |
| 9 a.m. | Araromi (Baptist) | Rev. A. A. Puddicombe |
| 5 p.m. | | Bro. John Apena |

EBENEZER (BAPTIST)

| | |
|---|---|
| 9 a.m. | Rev. E. C. Alabi |
| 6.30 p.m. | Bro. S. M. Phillips |

BROTHERHOOD

| | | |
|---|---|---|
| 7.30 a.m. | Ilupesi | Prof. Adeoye Deniga |
| 7 p.m. | | Pastor. A. Adedeji Iṣọla |

St. STEPHEN'S (EPETEDO)

9 a.m. & 4 p.m. Very Rev. J. G. Campbell

AHMADIA (ISLAM)

6 a.m. Fajir Service Y. P. O. Ṣodẹyinde

5.30 p.m. Open Air Service Imam K. R. Ajoṣe (Bamgboṣe Street.)

COLONIAL CHURCH (ODAN)

8 a.m.—Holy Communion

6.45 p.m.—Evensong and Sermon, Rev. H. A. Lewis

SALVATION ARMY.

Services at Glover Memorial Hall, 10 a.m. and in the Streets.

CHURCH OF GOD

10 a.m. 22 Ọdunlami Street, Breaking Bread

7.30 p.m. Campbell Street Open Air Service John P. A. Taylor, Wm. C. T. Terrell

---

MESSRS. J. R. THOMAS & SONS of Lisabi Hotel, Itori, beg to inform the public in general that they have been licensed by the Nigerian Railway to sell and serve refreshments etc. etc. to all passengers travelling on trains on up and down journey at Itori, Aro and Olokemeji Stations at very moderate prices. This venture has already been opened by them to the public at the aforesaid Stations, any one travelling up to Ibadan and back and needing supply of any kind of refreshment should intimate us through the Station Masters Iddo to Ibandan, and *vice versa*.

## AWỌN IWE ỌGBẸNI J. G. KUYẸ

Fun Ile Ẹkọ.

| | | |
|---|---|---|
| A. B. D. ALAWORAN | ... | 3d. |
| IWE ALAWORAN KINI | ... | 7d. |
| IWE ALAWORAN KEJI | ... | 9d. |

Awọn iwe wọnyi ko ti si lode ni sā kan nitori ogun Germani, sugbọn wọn tun de nisisiyi, a si le ri wọn ra ni Ile Iwe tita ti C.M.S ninu ilu yi tabi lẹhin odi.

Itan ati owe ti o wa ninu iwe wọnyi dara pupọ, bẹ gẹgẹ ni awokọ inu wọn dara fun ọmọde to, ẹniti o ba dan a wo yio ri pe ọgbọn ẹniti o ti jẹ olukọ awọn ọmọde fun ọdun pupọ li a fi to awọn iwe na lẹsẹsẹ, kişe işẹ *sare nbaja.*

A le ri awọn iwe wọnyi ra pẹlu lọdọ oniwe ni ẹdin owo, 66, Ibadan Street, Ebute Mẹta.

---

## IWE ITAN T'O KẸ RIRI

Ọrẹ,

Lọ ra Iwe Itan ti Ibadan ati ti Ọyọ ni Ile-itawe ti *C.M.S.* nibi, şile meji meji ati sisisisi ni a nta ọkọkan.

Ọgbẹni Isaac Akiyẹle l'o şe Iwe Itan ti Ibadan Ẹ o si ri owọ rẹ ninu ti Ọyọ pẹlu.

---

## BOOKS! BOOKS!! BOOKS!!!

"History of Ibadan" and "History of Ọyọ" by ISAAC AKIYẸLE are on Sale at the C.M.S. Bookshop, Lagos, 2/- 6d. each

---

"EKO AKETE."

A le ri Iwe-Irohin yi ra lọdọ Aşoju wa.

Ajenifuja Stores, 109 Broad Street, LAGOS.

Ọgbẹni VIDAL R. COLE.


## JUST THINK O



Persons desirous of selling or ac ring Houses or Land in the Colony Lagos should communicate with

E. SOYEMI ALDER

who for many years has specialised in th class of Property. Sales effected Public Auction or Private Treat Valuation for Mortgage or Proba carefully prepared. Loans arrange Commissions reasonable.

Please note address:—E. SOYEMI Auctioneer, Valuer, etc., Owode (o the Law Courts) Tinubu Square, Lago

---

## The Philharmonic Ban



Awọn oni fere yi nfun pętę, ilù nwọn si dun bi oyin l' eti.

Owo ti a nfi pe nwọn ko pọ, nwọn ko si kọ lati lọ si ilu kiilu.

Ẹni ba fẹ wọn, ko kọ iwe si

*THE SECRETARY,*

c/o Aafani Motors

The Marina Lagos.

**Preache**THER FACTORY.
AW ALAWO."

ROMAN Masse Aw... akoko w... ta (*sole-leather*) ti a șe ... o lẹ ti o si pupa yo, ati Awọ orișirisi awọ, yala ni pupa, ..n, dudu, ofẹfẹ, ati oriși awọ miran ni ...ni ọpọku ọyọku.




...o ba fẹ wa wo Ile Awo nla yi, ti iru ... si ni *Nigeria*, bi bẹkọ kowe șọwọ owosi :—

E. B. BEYIOKU-ALASẸ
108, Moloney Bridge St.
P. O. Box 368, Lagos, Nigeria.
*Telegrams*.—Alawobata, Eko.

## NOTICE.

When replying advertisers, please mention "Eko Akete".

## AKIYESI.

...ẹ ba fẹ lọ si ọdọ awọn ti o polowo ọja sinu ...e-irohin yi, ẹ jare ẹ sọ pe ninu iwe-irohin ...o Akete ni ẹ ti ri ipolowo ọja na ka.

## JACOB AJAYI,

*General Woollen Trader,*

has on hand Woollens in endless variety at 50, Dosunmu Street, Lagos, at

***Prices to suit everybody.***

*Call now, fortune awaits you.*

MR. E. ADE. OGUNMOKUN,
*GENERAL TAILOR.*
47, Princes Street, Recently Established
*Try me and see.*

## WO'BI.

Ile ọwọ ti awọn Ajọsẹ ti a npe ni Șabu Ireti nbẹ ti 24 Ita Agarawu nibiti a gbe le ri orișirisi ș'ẹrẹkẹ șin ati oti-amu-'nudun ra, si tun ni Ẹka Șabu kan ni 10 Ita Dosunmu nibiti ẹnikẹni le lọ ra ọja tirẹ ni ọpọku ọyọku.

Ọrẹ ikọwe si :—

Ọgbẹni SOLO. S. AJOSE,
*Alabojuto.*
ni 10, Dosunmu Street,
EKO.

## ẸNYIN ONIȘOWO EFO.

Ẹ wa polowo Ọja nyin sinu *Eko Akete*, kolẹgbẹ ni ede Yoruba inu re, o jare, o si "ka-yin, wọbọ-wọbọ."

Ẹ tete Isure wa. "Awure" nduro de nyin!!! Owo pọ ọ ni yio na ọ, ẹnikeji.

PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.